To The Chief Secretary to Government, Lagos

From D. A. Obasa Editor + Propr. Yoruba News Ogunpa Rd Ibadan

# The Yoruba News.

**FOR GOD, THE KING AND THE PEOPLE.**

VOL. I. No. 21. IBADAN, TUESDAY, JUNE 3, 1924. Price 3d. Weekly

CHIEF SECRETARY'S OFFICE 6 JUN 1924 LAGOS


## S. AGBAJE & CO.,

*General Merchants.*

HEAD OFFICES:
GBAGI & AYEYE MARKET,
Ibadan, Nigeria.

Suppliers of:
**Palm Kernels, Palm Oil, Cocoa, Maize, Rubber, Ivory &c., &c.,**
also
**MOTOR TRANSPORT SERVICE**
**Throughout the Western Provinces of Nigeria.**

CALL & SEE
## S. G. IROKO,
*HIGH CLASS TAILOR.*
At
Gbagi Street Iddo Gate,
Next, Door to Messrs S. AGBAJE & Co.,
IBADAN.

*For Your*
MORNING DRESS, DINNER JACKET, LOUNGE SUIT, EVENING DRESS, Etc., Etc., Etc.
In the latest
London Fashion,
AT RESOANABLE PRICES.

## L. L. RICKETTS,
*AGRICULTURIST.*
YEMETU STREET,
P. O. Box. 136. IBADAN.

Expert advice on the Agricultural Resource of Yoruba Land will be given to Amateur Planters on Application:—

Instructions with regards to Soil, Planting, Planting Seasons and the general routine of cultivation.
Selected, Plants of Gbanja Kola are supplied on reasonable terms and various useful plants including fruit trees etc., etc., etc.

Also: Instructions on the preparation, handling and storage of produce. An interview will prove interesting.
Correspondence will be carefully attended to.

## ỌRỌ DIẸ NIPA ỌBAṢEMI.

Ọwa, Igbimọ, Ilu ati Ẹgbẹ Atunluṣe, mo ki yin pẹlu ọpọlọpọ itẹriba, mo si tun bẹrẹ f'oji lati tọka si ọrọ pataki ninu ọrọ ṣoki ti Ọgbẹni wa Dr. O. Ṣapara sọ larin yin:-

O sọ Tun wa gbangba pe iru ipo ti Ọlọrun gbe oun si loni, Ẹkọ lo gbe oun de ibẹ; bẹ ni dajudaju lõtọ, o fi han wa gbangba pe ẹkọ ni agbara pupọ ati pe ẹkọ ni gbogbo ilaju ati ilọsiwaju ilu, eyi yi mu mi ranti ọrọ Ọgbẹni kan ninu iwe irohin Eko Akete ti oṣu *January* 26 1924. pe ọran iyàn ni fun ilu ti o ba nla kàkà ninu ilaju ati ẹkọ lati ni Iwe irohin tirẹ ati pe irufẹ ilu ti o ba nlaju ti ko ba ni Iwe-irohin tirẹ ṣi wa nipo ẹhin patapata.

Niti awa Ijeṣa mo fẹ ka mu Ẹkọ dipo Iwe irohin, eyi ti o ni lati jẹ ọran iyàn fun wa nitoripe a ṣi wa nipo ẹhin patapata nipa Ẹkọ.

Ẹ jẹ ka tun wo ọrọ Ọgbẹni wa Dr. O. Ṣapara daradara "Ẹkọ lo gbe mi de iru ipo ti mo wa loni" "Nitori nā awa Ijeṣa ni lati faramọ Oluwa Ọlọrun wa, ko jẹ ki ẹkọ mā pọ si i ni Ilu Ileṣa." Ọwọ wa loku si gān-pataki awa ọdọ ti a mọ riri Ẹkọ. Ẹ jẹ ka wo ọjọ jọjọ ti awọn Ile-ẹkọ Giga ti de Abẹokuta, Ibadan, Ijẹbu-Ode ati Ọyọ; lẹhinna o fo kọja lori Ileṣa bi òkò-ibọn, o sọlẹ si Ondo. Nitorina ẹnyin baba, arakunrin ati arabinrin mi, ẹ jẹ ka tẹ siwaju gẹgẹ bi Kristẹni Ologun, lati ran awọn ọmọ wa lọwọ pupọpupọ nipa ẹkọ, yio si jẹ inkan ayọ pupọ pataki fun awa ọdọ, bi a ba le ṣe gẹgẹ bi Ọgbẹni wa ti gba wa ni imọran dara dara yi. O ku sọwọ wa Ẹgbẹ Atunluṣe.

Emi ni ti yin nitotọ
Ọmọ Ibilẹ.

## "AWỌN AKEWI"
OR
## YORUBA PHILOSOPHY.

---

### ỌMỌ.

B' o ṣ' ori pàlàbà,
B' o ṣ' ori pàbó,
Ọmọ ni t' ẹni,
Edumare gbe t' emi ko mí,
Ọmọ ni t' ẹni.
Ọmọ dun kanhin,
Ju k' a m' ẹru ṣe 'le!
Ilit' ó mọ ni i j' ọmọ:
Ọmọ o l' ayọ le,
Ẹnit' ọmọ sin
Ng l' o bimọ.
Ijọ ti a ba ku,
Ọwọ ko gb' okowo;
Ọmọ ẹni ni i jogun ẹni.
Bi a ba lọ s' ajo,
T' a ko si ninu ile;
Ọmọ ni i wo 'le de ní.
Ọmọ da iya rẹ l'oju.
Kàkà ka b' ọgọrun ọbun,
Bi a bi ọkan ogo, o to,
Apà, òbùta, rairai,
Ọmọ Ọlọrọ Iṣāju,
Ni i ta Ilẹkẹ
F' ọmọ Ọlọrọ Ikanhin,
Ni i f' owo m' Ẹmu.
Ni i gb' Ẹṣin i ta,
Ni i f' owo i muti;
Ni i gb' owo Iwọ̀fa,
Ni i fi i sanwo f' ẹlẹran;
Ni i le Ẹru rẹ-rẹ-rẹ
Ni àle-wọ̀-'gbẹ́,
Ẹru ra wọ'nu igbo,
T' olowo d' egbe;
Ẹru sa wọ 'gbo tan.

Ẹru d' ọmọ ẹru lọ!
Ẹru sa ni ẹni.
N' dẹ ibikan dandan.
Elebà ,'e û i yà.
Ẹni bi ni l' ā jọ :
B' ọmọ ko jọ ṣọkoto.
A jọ kijipa.
T' oju ti inu l' ọmọ ẹni.
I fi i jọ ni ;
Ọjuọwọ ọmọ ni i
Jọ baba rẹ bi Imumu.
Bi kẹtẹkẹtẹ bimọ bi ko l' eti.
Ọmọ rẹ kọun, ọmọ-ọlọmọ ni ;
Bi Gambari bimọ bi ko r' ẹru,
Ọmọ rẹ kọun, ọmọ-ọlọmọ ni ;
B' Aja bimọ bi ko gbo.
Ọmọ rẹ kọun, ọmọ-ọlọmọ ni ;
B' Ọfọn-ọ̀ ba bimọ, bi ko jale,
Ọmọ rẹ kọun, ọmọ ọlọmọ ni,
Jọ mi, jọ mi, ni i sọ
Baba ọmọ d' onrórò.
Ọmọ ẹni i ba jọ ni
A ba yọ ti-ti-ti.
Awọn obinrin k' obinrin
Ni wọn ki i jẹ ki
Ọmọ ko jọ baba rẹ.
Akẹju ni i b' ọmọ rere jẹ :-
Ọmọ alagbara ni i lẹ.
Ọmọ Inọja a y' àpà ;
Ojo ni p' ọmọ olōgun.
Wọn i ba sun wọn ko ji,
Wọn a yi asọ mọri danyindanyin.
Ilẹ mọ tabi koi mọ ?
Eninin ro tabi koi ro ?
Ilẹ koi mọ, ọmọ mi
Jẹ 'lẹ o gbọn :
J' Eninin o ro :
Ki ngb' ọbẹ gbona.
Ki nra' iyan l'odo.
O jẹun o to ḿā lọ ;
"Iya, a gunyan tan.
A ti s' ọbẹ ka 'lẹ"
Alabi koi ti i ji.
Ẹ jowo rẹ ko sun ;
Isẹ wọn ā ṣ' lọ ju ni 'lẹnu.
Iwọh ōg l' a i osi
Ọmọ i sin lai s' ẹru.
K' o to i ji, ẹ f' omi le 'ra,
Ẹ b' omi s' agbada ;
E m' ọsẹ mu kànrinkànrin
Re Baluwẹ k'o to taji !
"Awodi ti nre 'Barà,
Efūfu ta a n'di pa a,
O ni " isẹ kukuya"
Ọbàjingin ko fẹ 'sẹ ṣe tẹlẹ.
Ọmọ olowo sun kākà yakata !
Alabi ọkin sun-sūn-sun
O na wọn-ọn, o yán Ilọ-o :
O nyi ka ori ẹni gbirigbiri !
Ni ibit' otoṣi ri orun
Ti ko r'aye sun,
Oun l' ọmọ olowo nwa ōrun
Kiri ori ẹni gbirigbiri !
Inọja ran ọmọ l' ọ̀fà,
Ọmọ k' ọrin pamọ ;
O ni ki oun o le ri
Ohun mā yọ na.
L' Ajò, l' Ẹhin odi.
B' ọmọ olōgun ba,
D' amure tan, a p' ẹfẹsẹ.
A mu Rukẹrukẹ lowọ :
A joko lọdọ awọn
Obinrin l' Ẹnu-odi.
Nwọn ni "E ti ri ?"
O ni baba ni ng má wa,
Ng mā tọju ile ;
Tani ko mọ p' oju ile
Dun i tọ ju t' Ẹgi lọ ?
Ẹgi mbẹ l' ọhun, ni dẹgidẹgi.
O ṣe Iya mi
B' Ẹkọ ba ku 'kan.
Ọmọ ẹni ng l' a i fun u jẹ.
Abiamọ ki i ku.
Ẹhin ni i fi ti opo.
Ọlọmọ ki i pẹ l' ẹhin odi
Isu ọmọ k' o mā jina fun ọ jẹ

# IṢE OLODUMARE DISPENSARY.



Joshua O. Ade: Craig,
*Manager & Proprietor,*
Established 1916.

LAGOS.
116 Great Bridge Street,

IBADAN.
Iddo Gate.

## KINI ṢE TI O FI RU BAYI?

Ikọ nwu ọ ni?
Ori nfọ ọ ni?
Inu nrun ọ ni?
Akokọro nba ọ ja ni
Otutu nmu ọ ni?

Mā bọ ni ile Egbogi ti a npe ni "IṢẸ OLODUMARE."

Ẹṣẹ ndun ọ ni?
Eti ndun ọ ni?
Ehin ndun ọ ni
Oyì nkọ ọ ni?

Mā bọ ni ile Egbogi ti a npe ni "IṢE OLODUMARE."

Iwọ ko ri Igbọnsẹ ṣe?
Iwọ nṣe Igbọnsẹ pupọ ni?
Oju ndun ọ ni?
Iwọ ko riran kawe ni?

Mā bọ ni ile Egbogi ti a npe ni "IṢE OLODUMARE."

Nkan-ki-nkan ti o wu ko ṣe ọ mā bọ ni Ile Egbogi yi, ni Gbagi odojukọ ile ọja Oyinbo Ajẹ (G. B. OLLIVANT). Ile Egbogi na ṣi silẹ lọsan ati loru, bi ọfẹ ni gbogbo rẹ, ti oju kan Alabojuto ibẹ yio tẹ ọ lọrun, iṛegbe ni yoku "Arùn ma jogun, ndagba si Ẹlẹda re."

Printed and Published by D. A. OBASA at The Ilare Press, Ogunpa Road, Ibadan

## Ẹ MA SỌ Ọ!
## KI NU U?
### OJO PATAKI
TI
## OIBO ALAGBON

(Ile Owo Ekini ni ile yi

yio si Ile-Oja Titun ti nwọn ṣẹṣẹ kọ si

BODE IDO, IBADAN.

Orişirişi Aṣọ, Iṣọṣọ Wọsiwosi, Awo Abọmafọ, Ohun-Elo onirin oniruru ati Ọpọ Orişi Ọja miran lo mbẹ nibẹ.

Ẹ MÃ ṢARAJỌ!!

---

**Ibadan Billiard Saloon.**

Ido Gate, Gbagi, Ibadan.
Opposite P. Z. & co.,
GAMES:
Billiard, Skittles, Dominoes, Draught, Ludo, Cards and Syrian Draught also Dancing
EXCELLENT MUSIC PROVIDED.

A Bar is attached for the convenience of visitors.

*M. K. Assaf,*
Manager Commission & Agent.

---

## TO LET.

---

## D. W. OKUSOTE,
*Tailor & Draper.*
Gbagi Street, P. O. Box 160, Ibadan.

All Kinds of Gentlemen's Garments accurately built in the latest style
Satisfaction Guaranteed.
Charges Moderate.
ALSO
Dealer in Machine & Cycle parts.
**Gents' & Ladies' Headwear**
Cheap! Cheap!!
PLEASE GIVE A TRIAL.

---

## HUDSON COLE,
*Builder and Contractor.*

*Undertakes & executes all kind of BUILDINGS & OTHER CONTRACTS in any part of Nigeria Plans & Estimates prepared.*

**Lagos Address:**
30,A. JOSEPH STREET.
**Ibadan Address:**
GBAGI STREET IDDO GATE.

# OWUYẸ.

## AFỌWỌRA.

Lawale Aburumaku ni awọn Onidajọ fi si ẹwọn oṣu mẹfa nitori o ji aṣọ iborun ati ọkẹ mọkanla 55/– ti Iyafin Nọfi Agodi gbagbe si inu Mọto ti Aburumaku fi wa Nọfi lọ si ile.

## EWU MỌTO.

A ki Ajẹlẹ Agba, Ọl.l. O õ,un W. A. Ross, oloye C.M.G. fun ewu a'ẹ Friday May 23, nigbati Mọto rẹ ko si kòtò ẹba ọna nibiti mọto Oibo Onigbo bọ si ni ijelo ni Atiẹ.

## RIPẸTỌ, KU IṢẸ O!

Ọgbẹni Talabi ati awọn oluranlọwọ rẹ lọ wo ọja Mọga ni *May* 23, ọwọ wọn tẹ mẹsan ninu awọn onirùkurà Ekuro ni ọja nā. Bālẹ ati Igbimọ da ṣẹria fun wọn nipa gbigba ọkẹ meji meji lọwọ ẹnikọ̄kan wọn, si apo Ijọba.

## OLE WỌ 'LU O.

Awọn ọlọṣa lọ ko ile Maya ni Oke-Ado ni oru ọjọ kẹrindinlọgbọn oṣu ti o kọja nwọn si tun ko ile..................ni Ekotẹdo ni oru ọjọ keji ni tẹle–tẹle.

Ọpa Ọba, Ọpa Bālẹ, E gba ni o.

## ṢINKUN AMỌDẸMORO.

Bi Babarinlọ ẹniti ọga rẹ, Ọgbẹni Okunọla, ran lọ i ra Tayà ni Ile-owo Faranse ni Satide *May* 31, ti mbere pe Elo ni ẹ nta Tayà? ni Ọlọṣa ọmọ Gambari ti njẹ Alakeuta ba fa owo yọ ni apo Babarinlọ. Ọpẹlọpẹ Afọlabi ti o ri i, Aboki i ba lọ gbe. Eyiti a nwi yi ti pẹ *Corporal* Ladele, Amunimada ti ki ọlọṣa nā mọlẹ: o di fi-ri-i gbaga ni Itimọle. Adajọ Ọgbeni Radford ti da ṣẹria ẹwọn oṣu mẹrin fun ole yi.

A dupẹ pe ọkan kuro ninu awọn ọmọ Jaguda nwọnyi.

## IJỌ ONITẸBOMI.

Awọn Ẹni-ọwọ L. O. Fadipẹ, Alakoso Ijọ *Baptist* Ẹkun Ibadan ati Ẹni-ọwọ J. R. Williams, Alufa Agba ti Ijọ *Baptist* l' Eko de si ibin ni *Friday May* 30 lati ba Ijọ wọn kẹdunnipa iku Ọgbẹni C. L. Ọdẹbiyi.

## IJADE ỌFỌ.

Awọn ẹbi, aya, baba, iya ati ọrẹ olōgbe Ọdẹbiyi jade ọfọ ni *Sunday June 1* Alagba Ẹni-ọwọ L. O. Fadipẹ ṣe iwāsu ti o kun fun ironu ti o si wọ ni lara pupọ de ibiti gbogbo enia ti nwọn wa ni ibi isin nā fi nda omi loju pẹrẹpẹrẹ; ẹkun ni baba arugbo oniwasu nā fi pari ọrọ rẹ; nigbati o si pada lọ joko, gbogbo Ijọ dakẹ lọ patapata ni iwọn iṣẹju meji, ti ẹnikan ko le mira. Iwāsu nā ka ni lara pupọ.

## OKU BI IBEJI.

Ni ọsan Ọjọ Isimi gān ti nwọn bọ de lati Isin Ijade ọ̀fọ̀ ni aya olōgbe Ọgbẹni C. L. Ọdẹbiyi bẹrẹsi i rọbi, ti o si bi Ibeji: awọn ọmọ mejeji si jẹ ọkunrin. Njẹ ayọ tun de, Babakọ̀lọ, Ọladipupọ.

Ki Oluwa da awọn ọ̀mọ nā si.

## ẸSAN NKE.

Ọkunrin kan yinbọn pa enia ni ọna Alabàtà, o si lọ fi oku nā pamọ si abẹ igbo. Ṣugbọn o sọ fun ọrẹ rẹ kan nipa ọrọ yi. Ara ọrẹ ko gba a, o si sọ fun wọn ni abule; ni ọwọ ba tẹ apania nā.

## IBERE LATI ABẸOKUTA.

Gẹgẹ bi a ti ri i ka pe awọn ara Ibadan nkede ki Balẹ, ati awọn Ẹni-ọwọ wọn le yọnda fun awọn Onigbagbọ wọn lati ni ibikan lẹhin odi fun Isimi ni ọjọ *Easter Monday*. Njẹ Eyin Ẹni-ọwọ tiwa nihin Ọgbẹni J. A. Lahanmi, J. J. Olumide ati Ramsome Kuti, ki yio ha fi si ero lati ba awa nā wa ibiti o ba le dara fun wa nihin?

Ọlọrun ko fi Iṣẹ yin nyin o.

"Ilękę ja si Ile ma ja si Igbę" a gbọ wipe lọwọ Ọgbẹni A. A. Martins lọ ja si. Ọlọrun kọ pe e ni Ise rẹ. Jọwọ mā sọra lọdọ awọn alagbedā o.

Agbọ wipe āwọ to ti wa larin Aminu Ẹgbẹyẹmi Ọtun Agọ Owu, pẹlu Suumọnu Akintoye Ṣoaga Sanmari Gbagura pari patapata, nję a ki awọn Gbajumọ mejeji yi nwọn ku sūru ;

A si ki Ọgbẹni Sanni Biobaku o ku aṣeyẹ nipa ọrọ yi. Ọlọrun kọ san Lada ni lọpọlọpọ.

## IJẸBU-ODE.

Empire Day Celebration at Ijębu-ode was attended by Their Highness the Awujalę, the Olowu, the Ajalọrun, chiefs Olisa and Egbọ and some prominent people together with all the School children also 12 Europeans.

The Resident Captain Borrough who was in full uniform arrived at 9.20. a.m the Flag was saluted by the singing of the National Anthem.

The Scouts played a notable part at the function also the presence of a Girl Guide in the person of the Mistress of Wasimi School, all the children had a most enjoyable day.

## News.

We extend our deep sympathy to the Revd. and Mrs. M. C. Adeyẹmi of Ondo Boys' High School, for the loss by death of their infant son, last week Monday.

Mr. Y. L. Ṣongoro had a narrow escape last Friday the 30th ultimo, when his bicycle collided with a motor car at the junct on of Agbeni Fọkọ Road Congratula ions!

Revd. J. F. Ade. Jones the Pastor of Holy Trinity Church, Kano came up from Lagos last Thursday May 29 and left for his Station yesterday June 2.

The continuation of the Bazaar by the Diocesan Women and Girls Fund is taking place to-day at the Township Court Hall.

To-day being the King's Birth Day, all Mercantile factories and Public Offices were closed.

## IGBEYAWO.

Atẹwe Irohin "Yoruba News."

Jọ bun mi laye bẹngan ninu Iwe Irohin rẹ lati dupẹ lọwọ Eni-ọwọ. I. M. Leninhun, Apọn Ọgbọn B.A., fun ọrọ iyanju rẹ nipa awọn obinrin Alárédè ni ọjọ Igbeyawo Ọgbẹni Eman Adeleke Adigun ni Ọmọfẹ Ilesa ti o han ninu Iwe Irohin ti May 13, 1924.

Iwà ọpọlọpọ ninu awọn obinrin Alárédè wa, pāpa awọn ti o ni ẹkọ *education* mu ki awọn ọkọ wọn kábamọ "Arédè." Pupọ ninu wọn ni a kọ ni Ile-ẹkọ giga ti awọn Ọmọbinrin ni Kudẹti, Ibadan, ni Eko ati ni Ijębu,lahẹ awọn obinrin oibo Misọnnari ti wọn si ni ipin iṣẹ wọn ojojumọ nigbati wọn wà nibẹ, gẹgẹbi: Ilẹ ... Ile fifọ *floor scrubbing*, ile pipa, oko titu, *weeding* ni akoko iṣẹ ọwọ *manual labour* ni ọjọọrọ tabi fun ijiya *bad mark* ni ọjọ Satide. A kọ wọn *they were taught* lati mọ akoko fun ohun gbogbo. Akoko lati ji bẹrẹ iṣẹ ati akoko lati pa'ngaṣun ode... Gbogbo eto wọnyi, ki iṣẹ ile ọkọ—ba—le mọ wọn lara ni. Ṣugbọn lẹhin ti o ti mérédè tan, iṣẹ ile gbigba ati iru iṣẹ kékéké bẹ di ohun ti o rẹ a ju fun ipo wọn lati ṣe, bi o ba jàjà diẹ lori ibusun ni agogo mẹjọ lọ si mẹsan, t' o wẹ ti tutu t' o fi *gore* kaba gba 'lẹ ja e o di ko ma kibosi 'Ojo o!' tete gba ilẹ yẹ tan ko wa lo da ina o. "Akinọlā iwọ lō pa'le loni o." Ka f'ọbẹ jona lori ina tan, ka ma kibosi-Akinọla ti npale pe oun ni ko tete lọ ro o nigbati oun sọ fun u. Ipari gbogbo rẹ ni idi pe, ori nfọ mi, ara nro mi ; ko ni ri bẹ ? Nigbati o ko lo ara rẹ lojojumọ ki o lagun ?

Ẹ wo Mrs. Burton ni Ọyọ, ọkan ninu awọn Ọga Ile iwe giga Kudẹti lati, akoko kan ko lọ lasan lati ipinsẹ, bi o ti nja firi lọdọ Kuku bẹni nju lọdọ awọn ti o fi sori iṣẹ gbogbo bẹni ko dawọ tirẹ pāpa duro.

Ẹnyin Iya wa agba obinrin, ẹ ba wa fi si ero lati tẹ ẹ mọ awọn ọdọmọbinrin leti ninu Ipade awọn Egbẹ obinrin ni ilu gbogbo, ki a le ri iyipada ati iṣiri lati ọdọ awọn obinrin "Alararédè" wa gbogbo.

## IROHIN EKITI.—JAMBOREE.

"Lẹhin orin Ọlọrun gba Ọba là" ni Igbakeji Commissioner wa lọ wo awọn Asia mẹta ti *Troop* Ọwọ, *Troop* Ifọn ati *Troop* Ado ri, ati bi nwọn ti ṣe lọ awọn Ọpa *Scouts* fun ọpọ Asia ati bi iru kokó okun ti nwọn lo. O si ri pe ti awọn *Troop* Ado lo dara ju. Lẹhinna awọn *Troop* Ikẹrẹ wa ṣe are kan ti a npe ni "Bibolọ Ejo" "*Skinning the Snake*" ati "Fifi Idiku ranṣẹ si ara wọn" "*Passing the Handkerchief*" nwọn si tun ṣe are mejeji yi pẹlu gbogbo awọn *Troop* mẹta yoku, awọn lo si gba ipo kini ninu mejeji. Lẹhinna awọn *Troop* mẹrẹrin wa ṣe are "*Passing the Message*" awọn ti o wa woran ati awọn *Scouts* si tuka nitori orun ti kan atari. Lẹhin onjẹ, gbogbo awọn *Scouts* ati *Scouters* wa yi ode ka "*Parade*" pẹlu ilu. Ṣugbọn rudurudu ti o wa ni Ilu Ọwọ likoko na ko jẹ ki wọn yi ode tobẹ; ṣugbọn wọn lọ si ile Ọ[illegible], [illegible], Asaba, ati Eberewe; wọn wa pada wa si ile lati lọ tete mura fun "[illegible] idi ina ninu agọ" "*Camp Fire [illegible]*" ti yio bẹrẹ ni agogo meje [illegible].

Lẹh[illegible] jẹ alẹ, gbogbo awọn *Scouts* ati *Scouters* lọ si Oke Akiti Ọṣọrun ni Ile Igbakeji *Commissioner* a si fun awọn enia die bi Ojiṣẹ Ọlọrun ni Ọwọ ati Ẹni-ọwọ M. C. Adeyẹmi *Principal Ondo Boys' High School* laye lati wa woran, iru Ipade bayi jẹ ti awọn *Scouts* nikan. Oriṣiriṣi are ati Itàkurọsọ ni wọn ṣe ni alẹ ọjọ nā, pẹlu oriṣiriṣi Igbe, ati Hihan *Scouts.* Lẹhinna, gbogbo enia tuka lati lọ simi.

Ni ọjọ kejì ti ṣe ọjọ *Thursday*, a tun bẹrẹ are ni agogo mẹjọ, awọn *Troop* ti Ifọn pagọ, awọn *Troop* ti Ado si tun ṣe are kan. Oriṣiriṣi ni awọn are miran ti a ṣe ni ọjọ na, Gbogbo awọn "Scouts" wa lọ si oke "Rest House" lati lọ wo awọn "Scouts" ti Ado nibi are inu Igbo "Stalking Game" awọn "Troop" yoku si ndi egbò, ati egungun ti o ṣẹ "Ambulance" Ni ipari gbogbo rẹ "Igbakeji Commissioner" pe gbogbo "Troop" jọ, o sọrọ iyanju fun wọn o si tu wọn ka. A sọ wi pe ki awọn "Scouters" wa pade oun n aṣalẹ ọjọ na ni oke Ile oun. i

Nigbati awọn Scouters de ibẹ o sọ oriṣiriṣi alebu ti "Troop" olukuluku fun, o si tun sọ ibiti olukuluku gbe ṣe daradara lẹhinna o wa sọ wipe ki a ṣiro gbogbo awọn ti oun ti ri pọ patapata ni ibi are, ni Iwọṣọ Ifetisilẹ si aṣẹ, ati Imura girigiri, ati Itẹle ṣe gẹgẹbi ọga olukuluku awọn "Scouts" ba ti sọ, ati iriasi awọn "Scouts" papa o sọ wipe oun ri ipo olukuluku "Troop" bayi pe:—

1. Ikẹrẹ "Troop"
2. Ondó, Ado ati Ọwọ "Troop" (dọgbadọgba)
3. Ifọn "Troop."

Bayi ni a fi adura tuka pẹlu ojo Ibukun ni alẹ ọjọ na.

Njẹ "Ohun rere kan ha le ti Nasareti jade wa?" "Jade wa wò." Nibi gbogbo ti a ti da "Scouting" silẹ ni Nigeria a ha ti gbọ pe nwọn ṣe "Jamboree" nibikan kan nibẹ bi? Fun eyi a dupẹ lọwọ Ọlọrun pe awọn "Scouts" ti Ilẹ Ekiti ni Ondo 'Province' lo kọ ṣe Jamboree ni Nigeria. Ati pẹlu ọjọ na gàn ni KING GEORGE V. ṣe "British Expire Exhibition" ni Ilu Oibo April 23 ọjọ na si jẹ ọjọ St. George.

A dupẹ lọwọ Igbakeji Commissioner ati Iyawo rẹ fun Itọju awọn 'Scouts' ati Aderin pẹlu fun pataki itọju onjẹ fun gbogbo 'Scouters' ati inudidun ati ara yiya ti nwọn ba wọn lo fun gbogbo akoko ti nwọn gbe ninu Ile wọn ni Ọwọ.

A nwo ọna fun Jamboree nla miran ti gbogbo Scouts Nigeria yio pejọ si ni ọjọ miran. A ṣe yi ṣe omiran o.

## IBADAN NEWS.

The Rev. L. M. Duval, M.A., General Secretary of the Nigerian Baptist Convention and the Rev. A. Adeniji Puddicombe, Director of the Ekiti Baptist Mission returned from their Missionary tour, on Monday the 2nd instant. They stopped for an hour to sympathize with the bereaved family of the late Mr. C. L. Ọdẹbiyi at Orita-mẹrin. They also visited the Revs. L. O. Fadipẹ, J. R. Williams, T. O. Dawodu and our Editor.

THE YORUBA NEWS.

*Editor & Proprietor:—*

D. A. ỌBASA,

*Office*-AJABA SQUARE, OGUNPA ROAD, P. O. BOX 60, IBADAN.

*Subscriptions payable in Advance.*

Ibadan 12s, per annum. 13s Post Free in Nigeria 14s. Abroad.

Cheques and Orders should be crossed and forwarded to the Editor.

Advertising rates &c. application.


## TRUE PATRIOTISM.

X.

ALTHOUGH forced to accept the modern and western civilisation at the point of the Bayonette and the boom of Artillery—only thirty-two years ago—Ijẹbu land is among the foremost of the leading and progressive Yoruba States.

When Governor Carter directed the British Troops to fling wide open the Gates of Jẹbuland for Free Trade, Evangelism and Light in 1892, who could have thought that there were so many talented prodigies lying buried under the thick clouds of ancient superstition and oppression that was then prevailing in the land? To-day her sons are second to none in the knowledge of the Arts and Sciences at every seat of learning wherever they may gain admission.

The result is, that we now have amongst this tribe, eminent Divines, renowned Doctors of Medicines, brilliant Lawyers, accomplished Journalists, reputed Educationists, noted Artists, men of high intellectual attainments and they are also acknowledged keen and clever dealers in the arena of trade. Above all, Ijẹbuland is fortunate in having among her Leaders, Princes and Rulers, men who have reaped and are now reaping the benefits of western civilisation.


ASAN-SILE NI OWO GBIGBA RẸ

| | Ibadan. | Ilu miran. ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6,6d. | 7/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.


The late Mr. Joseph Odumosu, the famous Native Physician of Ijẹbu Ode, was a man of outstanding qualities which he utilized largely for the benefit of his country. With the scanty knowledge of reading and writing acquired under very great dis-advantages, Mr. Joseph Odumosu was able to collect and preserve for the use of the Yoruba race, Recipes for Herbal Remedies as practised in the country from time immemorial. His "Iwe Egbogi" and the revised "Iwe Iwosan" are standard works on this subject and which had at the same time revealed deep knowledge of the Healing Arts possessed by our ancestors. His was the first privately owned printing plant outside Lagos. These show the extent of real patriotism latent in him.

Although it is common to see a number of amateur painters and dabblers—especially among the school children in the large towns in Nigeria, the honour of being the first distinguished West African Artist and Painter of International fame is reserved for Mr. Aina Ọnabolu, a native of Ijẹbuland, who started painting like many other amateur artists in the country, and has scientifically developed his love of Art to such an extent that he felt it his duty to relinquish his substantial post in the Government service in favour of his profession.

Mr. Ọnabolu's Art Exhibition at Empire Hall just before his departure for England was an eye-opener to the intelligent community. His successes whilst in England as a student of the Royal Academy is unique in the history of British West Africa. To-day we can

boast of many beautiful portraits of high government officials, church dignitaries and social leaders—skilfully painted by this Nigerian Artist.

The greatest compliment ever conferred by Government on any private individual is the honour of painting and decorating the Nigerian Stalls at the British Empire Exhibition now holding at Wembley Park, London.

As it is well known, it is not an easy matter to be an artist. Mr. Ọnabolu's road to fame was not strewn with roses in attaining to eminence along this un beaten track. He had to travel through numerous disappointments and hard experience before gaining his object in life, his patriotic spirit soared high above obstacles until he secured the foremost place among the leading lights of his race and country.

---

## Iparoko.

Si Oniwe "Irohin Ilẹ Yoruba" Ibadan.

"Alasọ ni pe asọ rẹ ni akisa ti ā bā pē bẹ̀. Eyi ti mo fi pari ọrọ mi ni ijelo ni pe, o yẹ ki a ni "Iwe Itan Ilẹ Yoruba" ni ede tiwa pāpā, fun anfani awọn ọmọ wa, ati awọn ti ko le ka ede oibo ti wọn fi tẹ iwe yi.

A si ro pe awọn "Ẹgbẹ Agba-o-tan" to gbiyanju lati tẹ iwe "Itan Ọyọ, Ibadan, Iwo, Oṣogbo,ati Ẹdẹ," nipa inawo wọn, yio gbiyanju lati tun ṣe inawo iwe yi fun anfani Ilẹ Yoruba.

Ọpẹ yẹ ẹniti o ti ṣe akojọ awọn itan wọnyi eyini ni Ọgbẹni Isaac Babalọla Akinyẹle, Ẹ ku iṣẹ, ẹ ku wahala o! Ṣugbọn a nreti pe bi awọn ẹgbẹ na ba yi iwe yi si ede Yoruba,(Poun kan £1-1-0 Ṣile kan ni wọn nta iwe nā ni Ile-Itawe ti awọn C.M.S. ni ibi gbogbo,) ko ni ni inọwo tobẹ̀ mọ, owo rira rẹ yio dinku; nitori akoko ogun ti gbogbo nkan nwọn geregere ni wọn ti tẹ iwe yi.

"Alasọ ni ipe asọ rẹ ni akisa ti ā bā pē bẹ̀"

Bẹ̀ si ni awọn enia wa nta ara wọn fun awọn oibo ni okowo, ti ẹgbā ko si to lati ra wọn pada mọ. Ni ibi gbogbo ni a nri iru eyi ni ibi iṣẹ Ọba, Reluwē ati Onisọwo. Ẹniti o gbi iru ebu ika bẹ̀, ki o da a l'oju pe, yio hu l' ori ọmọ rẹ: ki oun pāpā to ku ni yio mā ri eso iṣẹ rẹ.

Ohun to kan wa lati ṣe bi ẹnikan ba nhu wa aitọ si wa ni pe, ki a fi iwa aitọ gun u loju,bi ko ba fẹ, ki a gbe e siwaju awọn to tun jẹ agbà. mo si ro pe bi oun pāpā ki iba ṣe ọmọlangidi, yio yan mu ninu ọrọ otitọ ati ohun ti iṣe alafia

Ni ọna kini, ofin Gẹsi ko da ẹnikan si: ibā jẹ ọba, ọmọ-ọba, ẹrū ọba, bālẹ, lọya, awọn adajọ pāpā, olowo, ati akuṣẹ, ẹniti o ba lu ofin, ofin a si lu oun nā di i. A ni ireti pe awọn Ijọba Ibilẹ. (Native Administrations) yio tun igbimọ wọn ṣe daradara, ti yio jẹ pe bi ẹnikan ba hu iwa aidara, yala ọkan ninu awọn igbimọ ni o,tabi ọmọ ilu ni, ti wọn yio to lati dajọ rẹ larin ara wọn ni ọna ti o tọ ti o si yẹ.

Ẹ jẹ ki a ranti pe awọn oibo joko ti wa lati mā ran wa lọwọ ki alafia le wa ni ilu ni, ki a jūmọ damọran pọ, bi ilu o ti ṣe toro: ki talaka maṣe yaju si Ọba ati awọn olori, ki awọn olori masi ṣe rẹ awọn talaka ibẹ jẹ, ṣugbọn ki alafia o wa fun gbogbo aiye, ki ohun rere si mā wọ ilu wa ni akọtun, idi eyi ni awọn oibo fi wa larin wa.

Njẹ bi awọn oibo ba nwa alafia wa, melomelo lo yẹ awa pāpā lati mā wa alafia ilẹ wa,ki a si mā le pa rẹ. Ki a le mọ pe awọn oibo nfẹ alafia ilẹ wa, wo ofin "maṣu matọ" ni Eko, ati a ngba owo ohun ốfố ti obinrin ti o yatọ si ti

ilu yoku ; nitori ko dara fun awọn ara ilu oke, nwọn ko si pe dandan gbọn, ki wọn gba a ; ofin ti Ijọba Ibilẹ ba ro pe yio dara fun ilu wọn, awọn oibo ko lodi si i lati gba a, ṣugbọn lẹhin ti wọn ba ti pari rẹ tan, ko tun da ẹnikan si mọ titi de ọba ori itẹ. Eyi ni ko ye awọn olori wa, nigbati wọn ba lu ofin tan, ti ofin ba si lu wọn san, nwọn a ni "aiye di aiye oibo," aiye di aiye oibo lōtọ, ṣugbọn nitori ko le rọ gbogbo aiye lọrun ni awọn Ajẹlẹ ati awọn oluranlọwọ rẹ titi de Gomina ( Governor ) to wa lori wa fi wa lọdọ wa. Bẽni ko si ọkan ninu awọn olori wa wọnyi ti a o mā jẹ niya nitori o lu ofin ti inu wa yio dun si i ; nitori Owe Yoruba sọ pe:— "Pa ọmọ mi ni igbe fun mi, ki ide inu abiamọ."

(Kọi iti i pari).

## ỌFA NEWS.

The Honourable H. B. Hermon-Hodge Resident of Ilorin, came on inspection on Thursday 22nd and returned to Ilorin, on Monday 26th instant.

On Sunday, 25th instant, Memorial Service of the late Mr. William Samuel Randle, Agent of the African Christ Church, was held. Mr. and Mrs. Joseph Ade: Adebimpe also Mr. and Mrs. E. Ọla: Aina accompanied by Mr. Daniel A. Superbus Vaughan gave two beautiful songs for this occasion. The service was well conducted and largely attended.

FOR SALE.

FORD CAR

APPLY:— R. L. BOWEN,

A.D.O. OSHOGBO.

## Kaduna News.

### ARRIVALS.

Mr. L. John, Goods clerk, Nigerian Railway from Zaria arrived on Friday 23rd instant to take up duties in the Goods shed at Kaduna Junction Station.

Pa—Mr. Nol, P.W.D. Fitter arrived on Saturday morning the 24th instant from Gold Coast his country where he had gone to spend his leave a few months ago.

### ARREST.

An Asaba young man, Tom by name was arrested from Kaduna Junction last Thursday the 22nd ultimo at about 5 p.m. for stealing his European Master's Kerosene. On being marched by a police escort through the town with hand-cuffs, the shameless vain rogue was smoking cigarette along, bluffing over the serious indictment against him and " King's Bangles" on his hands. He was convicted and sentenced to two months' imprisonment on Friday the 23rd instant.

### CONTINUATION OF LAST REPORT OF A CONVICTED PRISONER.

The convicted prisoner for assaults reported last that went to his European for a loan of £6 had returned with failure and is now serving his four months in jail.

### DEPARTURES.

Mr. Salakọ, Goods clerk Kaduna Junction left here on transfer to Zaria, vice Mr. L. John transferred to Kaduna Junction.

### Obituary.

Mr. P. C. Ejo, clerk in the Niger Company was bereaved of one of his daughters on Saturday morning the 14th instant. We tender our sympathy.

### CELEBRATION OF EMPIRE DAY.

The usual parade for the occasion took place in the Parade Ground of the Nigeria Regiment.

The function started at 7. 50 a.m. when the Lieutenant Governor arrived.

He first inspected the rank & files of the Soldiers, next thing he presented a medal tọ an old Soldier who marched forward in his large blue gown and spotted turban. Then followed the Royal salute and then 21 Cannon firing in succession with Royal salute (National Anthem) after every 7th, followed.

Artillery Drilling was the next event just at this time, Mallam Aminu came in, in his Go-cart drawn by a horse. Two Drummers followed him on horse back; they had to content themselves standing afar off the field where they could best see. The L. G. gave a short address interpreted into Hausa by one of the Soldiers. Display of various musical drills followed and the function was brought to a close at 8.45 a.m., when the L. G. left the field.

### Mr. Peters

the Lieutenant Governor's Motor Driver.

One was greatly surprised to see Mr. Peters steering the L.G's Motor Car so vigorously this morning on the parade field, after all the enjoyments in the African Club House the whole of last night when Concert was given in the Merry House and other merriments served.

Mr. Peters appears fresh this morning as if just arrived from Sierra Leone his country.

### Posts and Telegraphs and Public HOLIDAY.

Two successive public Holidays had fallen on Mail Days this year to the disadvantages of the Post Office clerks, namely: Saturday before Easter and Empire Day.

While others were enjoying the scene of various displays on the parade field on Empire Day, others made their way to the Post Office anxiously pressing for their letters. We particulary commend the good temper of Mr. A. A. Adẹṣẹyẹ the Postmaster, to the public. His actions show politeness, gentle and kind treatment of the public. We say this that the whole staff there may know that the public watch each individual's treatment of the public. One who patiently and politely deals with rude, and impatient public is not a fool, he will surely and successfully rule people of whatever sort.

## Ibadan News.

Messrs. Alex. Lewis, D. B. Akerele and C. M. Silva came up on a flying visit on Empire Day to attend a solemn Requiem Mass which was sung at Oke Arẹ Seminary, for the repose of Mr. Alex. Lewis son who was drowned last Easter Monday.- R.I.P.

### AN ACKNOWLEDGEMENT.

We have received from the Chief Secretary to Government copies of the "London Times" British Empire Exhibition Number of April 23, with thanks.

### EDE ELEDE.

Ki lo ṣe ti-a gbadun lati ma sọ ede oibo nigbati a ba pade Yoruba ara wa lọna ti a jọ gbọ ede ara? Bẹni ọkunrin kan lọ si ọdọ Dokita to wa ni ọkankan G. B Ollivant, eyiti iba fi sọ ede Yoruba ti o gbọ, o de ibẹ o ko oibo palẹ; bẹni o nṣe apejuwẹ gẹgẹ bi aisan ti mba enia oun ja, ni o nfi ọwọ kan ẹgbẹ ọtun o nfi ọwọ kan osi ati gbogbo ara-bẹni oibo ni o nsọ, ṣugbọn ki ba kuku sọ ede Yoruba, Dokita to kọ Iṣẹ yi to si ti mọ awa Yoruba ati ede wa, bi a ba sọ fun u yio mọ ohun ti yio ṣe. Nitorina ki a ma gberaga nitoripe Egbogi Dokita ko ri bẹ. Mo yin Iṣẹ (Olodumare Dispensary) pupọ fun sūru ati āyan ti ọ fi nṣe iṣẹ rẹ

Si Oniwe Irohin (Yoruba,) Ibadan.

Ọmọde ni ōkan lọwọ o, ni oun o digbolu Eṣu?

Hawu! Ẹ rọra diẹ, ẹnyin ara Ikẹrẹ, kekere kọ mā ni Iya ọmọ fi ju ọmọ lọ o. Eyi ni nipa Ilẹ ti awọn ara Ado ati Ikẹrẹ nja si larin ara wọn. Lẹhin igbati a gbọ pe Ajẹlẹ D.O. to wa li Ado Ọgbẹni Clegg ti pari ija nā fun wọn, ni a tun gbọ pe awọn ara Ikẹrẹ ti kūn pe ko tẹ wọn lọrun ati pe Ọba wọn Ogoga sope ki Oibo fun wọn laye ọsẹ kan perẹ ki oun ati awọn ara Ado le fi ja: bi o ba jẹ pe otito ni Ọba wọn sọ bẹ a bẹ Ijọba ki o ki irufẹ Ọba bẹ wọ, ti o fẹ ba alafia Akoko ti o dun bi oyin bayi jẹ, ko si Ọba ti o wa ni Ile Yoruba ti ko mọ pe Ile-Ifẹ ni Ọba Ewi l' Ado ti wa.

Ninu ilu yi ni awọn ara Ikẹrẹ ti jade lọ, ilu Ikẹrẹ ati Ọba rẹ jẹ ti Ẹwi pẹlu.

Orin asha:— Ẹ jẹ lọ ma Agba lẹgbọn, Ẹ jẹ lọ ma Agba lẹgbọn Elewi lọba.

*Koi ti i pari*